# Ọjọ Adura Ẹgbẹ Obinrin Onitẹbọmi Lagbaaye
Ọdun 2017

## Ori Ọrọ: Dide Tan Imọlẹ

## Nigba ti A Ba Tan Imọlẹ Ayipada Yoo Ba Agbegbe Wa

**Ẹ Palẹmọ fun Ọjọ Adura**

1. Ẹ gbadura ki ẹ si palẹmọ fun eto ti yoo mu ki awọn eniyan ni oye ohun ti ẹgbẹ obinrin Ijọ Onitẹbọmi n ṣe ki o le ni ipa lagbaaye fun Kristi bi wọn ṣe n DIDE ti wọn si n TAN IMỌLẸ. Awọn igbimọ ti o n palẹmọ fun eto yii gbọdọ pinnu ọna ti wọn le gba gbe eto naa kalẹ lati jẹ ki o rọ awọn obinrin Onitẹbọmi lọrun. Ọjọ Aje, ọjọ Kẹfa, oṣu kọkanla ni a ya si ọtọ ni orilẹ ede Nigeria ati ni gbogbo agbaye.
2. Ẹ polongo eto DIDE TAN IMỌLẸ pẹlu aworan alẹmọgiri. Ẹ pese apowe fun ọrẹ pẹlu awọn ẹkun kọọkan. Ẹ gba awọn eniyan niyanju lati fi ọrẹ ti o jọju sinu apowe ki a le ṣe ohun ti o jọju ni agbaye. Awọn awọ ti a n sọ niwọnyi: Afrika – elese aluko, Asia – buluu olofeefe, Caribbean – awọ eweko, Europe – buluu ti o dudu, Amerika – awọ esuru, North Amerika – olomi ọsan ati South West Pacific – awọ pupa yoo. Ni ara apowe ẹ fi ami idanimọ Dide Tan Imọlẹ si lara pẹlu aaye fun orukọ ati iye ti ẹnikọọkan da sinu rẹ silẹ.
3. Ẹ jẹ ki olusọrọ yin ọjọ naa fi aaye silẹ fun ijiroro ati lati ronu lori iriri wọn lori ayipada ti o ba aye wọn ati ipa ti o ni lori idile wọn ati agbegbe pẹlu ile-iwe, ẹnu iṣẹ, ọrẹ ati bẹẹbẹẹ lọ. Ẹ fi aaye gba wọn lati dupẹ lori awọn ayipada wọnyii.
4. Ẹ ka ẹbẹ adura lati ẹkun Africa ati eyi ti o wa fun ẹka ẹgbẹ obinrin ati ẹgbẹ obinrin ti Africa tabi ki ẹ pin awọn ikọ si ẹka keekeeke ki wọn o le gba adura naa daradara nipa kikuro ni ojukan pẹlu awọ ẹkun ti wọn ba n gbadura fun. Bi o ṣe dara julọ ni ki gbogbo obinrin ni apapọ gbadura fun gbogbo ẹkun. Ẹ le ṣe keekeeke ti yo tun jẹ ki ẹ le sọ awọn nnkan kan nipa awọn ẹkun wọnyi pẹlu awọn aworan ti o ba yẹ ki ẹ le ṣe afihan ifọwọwọwọpọ ti o wa .
5. Ẹ pese apowe fun ọrẹ ni oriṣiriṣi awọ. Ki ẹ si fi ami Dide Tan Imọlẹ ṣe ami sii. Owo ọrẹ yii ni a fi maa n ṣe awọn akanṣe iṣẹ ni orilẹ ede, agbaaye ati ẹkun kọọkan. Ẹ fi owo ọrẹ yii ṣọwọ si Olu Ile Iṣẹ Ẹgbẹ Obinrin ni ilu Ibadan. Orukọ ifowopamọ ni Baptist Women's Missionary Union of Nigeria. Nọmba ni 1010394132, Zenith bank.
6. Ẹ pe awọn ọmọ ẹgbẹ Irawọ, Wundia, Lidia ati Ẹgbẹ Obinrin Agba si eto naa.

**Adura**

**Orin Iyin**

**Ipe Si Isin**

**Ẹ Dide Tan Imọlẹ**

Ikini lati Ọdọ Alaga BWA Ẹka Ẹgbẹ Obinrin Lagbaaye

Ni ododo, kii ṣe ohun ti o ṣoro fun obinrin lati dide tan imọlẹ. Ni aiwo bi o ṣe le ri. Iwadi UN fihan pe ti o ba di ọdun 2020 agbaye le tin i ẹkunwo ti o to mejidin-lọgbọn tirilọnu owo ilẹ okere dọla ti awọn obinrin naa ba ko ipa gẹgẹ bi o ti yẹ. Ṣugbọn pẹlu bi nnkan ṣe n lọ o ṣeeṣe ki o to ogoje ọdun lati de erongba yii.

Bi mo ṣe n woo nipe ilaji ẹbun ti o wa ni agbaye ni wọn n ṣe amulo tori pe o dabi egun lati jẹ ki awọn obinrin ko ipa ti wọn ju gbogbo rẹ lọ, wọn n tọ awọn ọmọbinrin bii ohun elo ẹlẹgẹ, ẹni ti ko ni ẹkọ iwe bi o ṣe yẹ, ẹni ti o jẹ pe ohun ti o wa ṣe ni aye ni lati gbe igbe aye, lọkọ ki wọn o si bimọ lasan. Eyi ko gbọdọ ri bẹẹ ninu ijọ Ọlọrun lapapọ ati ni aarin obinrin Onitẹbọmi tori pe a gbagbọ pe Ọlọrun ti kan awọn egun aye wa mọ agbelebu, o si ti pa awọn egun gbogbo run, ti o si ti sọ awa obinrin ati okunrin pẹlu ji si aye titun nipasẹ Ẹmi Rẹ (*Romu 8:3-4*).

Kii ṣe ohun ti o buru lati jẹ iyawo tabi iya. Bibeli si fi idi rẹ mulẹ pe ki a maa tẹriba fun ara wa ninu ifẹ Kristi. Ohun akọkọ ni jijẹ iya- eyi jẹ ẹbun iyanu lati sọ di pupọ ki a mu dagba igbe aye miiran ti o kun fun ẹbun si araye. Ọlọrun fi aaye gba obinrin lati kopa ninu iṣeda kii ṣe nipa jijẹ iya nikan. O fẹ ki o kopa pẹlu awọn ẹbun ti O fi fun wa ati iriri fun anfani araye. Iyọnda ara ẹni jẹ eso iyanu iwa bi Ọlọrun ti o le mu ki nnkan rọgbọ ni agbegbe. O jẹ ohun ti o dara fun ọmọlẹyin Kristi patapata ni aifi ti boya ọkunrin tabi obinrin ṣe nitori ti Kristi (*Efesu 5:21*) o yatọ si ifiyajẹni ninu ẹmi ati ara ti o jẹ iriri obinrin lati ọdọ awọn ọkunrin. O ṣe ni laanu pe awọn ọdọmọbinrin paapaa n fi oju wina irora ilokulo lati ọdọ awọn iya, iya agba ati awọn ẹlẹgbẹ wọn. Wọn a tilẹ maa sọ fun wọn pe bi awọn naa ṣe laa kọja niyi, awọn naa gbọdọ mu u mọra ni bi ẹṣẹ naa ṣe wa ni igbekalẹ niyi lati maṣe jẹ ki obinrin le lo awọn ẹbun ti Ọlọrun fi fun wọn. Bi awọn obinrin ṣe n yọnda ara wọn ninu laaṣigbo niyi. Wọn n kọ lati wa laaye ṣugbọn wọn ko ni anfani lati tọ omi iye lẹkunrẹrẹ ti Jesu fi fun wọn wo. Wọn ko si le di kanga omi iye fun iyipada ni agbaye (*Johanu 4*). Ko yẹ ki eyi ri bẹẹ Jesu pe obinrin lati yipada ki wọn o si di ẹni ti o n yi agbegbe wọn pada. Ijọ Kristẹni ko le mu ofin nla ṣẹ ti o ba jẹ pe lori lilo ilaji ẹbun wọn ni wọn duro le lori. Nitori naa, iran kan wa fun obinrin lati mọ pe ọpọlọpọ obinrin ni wọn lo ẹbun ti Ọlọrun fi fun wọn ninu Bibeli ti wọn si yi awọn orilẹ ede pada. Wọn kan maa n darukọ awọn obinrin yii lerefe ni lori aga iwaasu tori pe ko ba ipo ti araye fi obinrin si mu. Ẹ lọ ka akosilẹ orukọ awọn ti o ba Pọọlu ṣiṣẹ pọ ti *wọn si mu ayipada, ba aṣa ati aye ni Romu 16. Ko le si iṣegun fun Israẹli ni aisi Deborah (Onidajọ* 4:4ff) ni aisi Lydia ni Filipi ko le si ijọ, ni aisi Maria ko le si Jesu. Awọn ara Samaria ko le gbọ ihinrere ti ko ba si obinrin ara Samaria ti o fi koto omi rẹ silẹ ti o mu ihinrere wọ inu ilu lọ nipa Jesu. Nigba ti awọn obinrin ti Ọlọrun ba dide ni Ọlọrun to n mu ayipada wọ inu ilu ati agbegbe rẹ.

Ksenija Magda
Alaga 2015-2020
BWA Ẹka Ẹgbẹ Obinrin Lagbaaye

**Ẹ Dide Tan Imọlẹ: Nigba ti A ba Dide Imọlẹ Yoo Tan**

A pe yin si "Dide Tan Imọlẹ" ni ọjọ kẹfa oṣu kọkanla ọdun 2017. Ẹka ẹgbẹ obinrin Ijọ Onitẹbọmi Lagbaaye pin si ẹkun meje ti o si n ṣoju ẹgbẹ onitẹbọmi mẹta le ni aadọwa lati orilẹ ede mẹrindin ni ọgọjọ. Awọn Ẹgbẹ Obinrin Ijọ Onitẹbọmi ti Africa (BWUA) ni wọn ṣe agbekalẹ eto ti ọdun yii.

Dide Tan Imọlẹ: Ọjọ Adura Ẹgbẹ Obinrin Lagbaaye.
BWA Women's Department 405N Washington Street Falls Church, VA
22046 USA Tel: +1(703) 790-8980, Ext. 148
Fax: +1 (703) 663-8269
Email: womenbwa@bwawd.org
Web: www.bwawd.org

Ẹ Dide, Tan Imọlẹ: Nigba ti a ba dide ayipada yoo ba agbegbe gbogbo. Alafia fun gbogbo obinrin Ijọ Onitẹbọmi ololufẹ tootọ. O jẹ akoko ati anfani nla lati gbadura gẹgẹ bi ọmọ Ọlọrun fun agbaye. Mo gbagbọ pe a o ni iriri iwalaaye Ọlọrun bi a ṣe n wa oju Rẹ. Ipe Ọlọrun ni pe ki gbogbo obinrin dide ki wọn o si kigbe pe Ọlọrun ikore ti o ni idahun si awọn ipenija gbogbo ti o n koju agbegbe lonii. Eto Ọjọ Adura ni Agbaaye ti ọdun yii ni o jẹ pe Ẹgbẹ Obinrin Ijọ Onitẹbọmi Africa ni o gbe e kalẹ (BWUA). Ohun ti o wa ni aarin gbungbun adura ti ọdun yii ni ipe obinrin si iṣẹ isin ti a o fi sọ nipa ayipada igbeaye pẹlu agbara Ẹmi Mimọ nipasẹ gbigba Jesu ni Oluwa ati Olugbala wa. Jesu wa lati sin ati lati yi igbe aye eniyan pada ni gbogbo agbegbe. Ojuṣe gbogbo wa ni agbaye niyi loni gẹgẹ bi ọmọ Ọlọrun ni aifi ti bi a ṣe dagba, idile ti a ti wa ṣe ṣugbọn Bibeli n pe Kristẹni lati "maṣe dara pọ mọ aye ṣugbọn ki a yipada lati di titun ni iro inu wa, ki awa ki o le ri idi ifẹ, Ọlọrun ti o dara, ti o si ṣe itẹwọgba ti o si pe (*Romu 12:1*). Bakan naa ninu ihinrere *Luku 19:10* Jesu Oluwa sọ pato ohun ti o jẹ erongba Rẹ ti o fi wa si aye eyi ti o jẹ iṣẹ wa ni pataki ati ojuṣe wa si awọn agbegbe ti a n gbe pẹlu eniyan. "*Nitori ọmọ eniyan de lati wa awọn ti o nu kiri ati lati gba wọn la.*"

Gẹgẹ bi iwe atumọ ṣe sọ pe ayipada tumọ si "ayipada pataki tabi patapata". Awọn eniyan ti o gbadura lati gba Jesu Kristi ni Olugbala wọn a maa di atunbi nipasẹ Ẹmi Ọlọrun bi wọn ba ti di ọmọ Ọlọrun. Awọn wọnyi di atunbi pẹlu iye Ọlọrun lati inu wa. Ẹmi ti o wa ni inu wọn a maa mu wọn pọngbẹ lati mu iyipada ba aye awọn Kristiẹni si irisi Kristi fun ete ti Ọlọrun. Ki ayipada yii le wa sibẹ, eniyan nilo lati maa fi ounjẹ Ọlọrun bọ ara rẹ, nipa kika Ọrọ Ọlọrun ni ojoojumọ ki ẹ si ni igboya lati duro ninu aṣẹ Ọlọrun ki ẹ si ṣe ohun ti Ẹmi ba dari yin lati ṣe ki ẹ si yipada si irisi ọmọ Rẹ.
Ayipada ti o ba waye yii kii ṣe ti ẹnikan ṣoṣo mọ. A le jẹri pe ti obinrin ba fi igboya yipada, yoo kan ẹbi ati awọn aladugbo si igbe aye ti Ọlọrun. Ẹmi Ọlọrun ni ẹmi otitọ ti ayipada pipe si yẹ fun agbaye. Nitori naa, ẹyin arabinrin, ẹ jẹ ki a dide, tori pe ti a ba dide, Ọlọrun yoo tan nipasẹ wa yoo si mu ayipada ba agbegbe wa.

Tiyin ninu Kristi
Joina Dhlula
Alaga BWUA

## Ẹkọ Bibeli

**Dide Ki O Tan Imọlẹ:Nigba ti O Ba Dide, Oun Yoo Mu Iyipade Ba Ọkan Kọọkan**

*"Wọn si wi fun obinrin naa pe, kii ṣe nitori ọrọ rẹ mọ ni awa ṣe gbagbọ: nitori awa tikara wa ti gbọ ọrọ rẹ, awa si mọ pẹ, nitootọ eyi ni Kristi naa, Olugbala araye" (Johanu 4:42)*

**Ibẹrẹ**

Kristi ninu aye rẹ a ma mu ayipada wa sinu aye lati jẹ ki o gbe igbe aye ti o n lẹle Kristi ti o yatọ si ti aye Pọọlu gba awọn kristẹni ni Romu ni iyanju lati gbe igbe aye mimọ, ki wọn o maa pọ si ninu igbagbọ ki wọn o si maa ṣe afihan ifẹ Ọlọrun. O gba wọn niyanju lati maṣe darapọ mọ aye ṣugbọn ki wọn o yipada nipa iwa bi Ọlọrun *(Romu 12:2)* Eyi ni o le mu wọn tẹ Ọlọrun lọrun ti wọn yoo si tan fun-Un, Ẹ jẹ ki a ṣe agbeyẹwo obinrin kan ti ayi pada aye rẹ fa ọpọlọpọ wa si ọdọ Jesu Obinrin ara Samaria *(Johanu ori kẹrin)* O ti gbe igbe aye ti ko bojumu nigba kan ri ṣugbọn Jesu Kristi fa soke ninu igbe aye ainireti ati aisiiranlọwọ. Fun idi eyi o kọ igbe aye atijọ rẹ silẹ ti o si n gbe igbe aye titun ti o dara ninu Kristi. O dide o si n tan ti o si n sọ nipa bi o ṣe ba Jesu Kristi pade ti o si n tan ihinrere iriri rẹ titun kalẹ nipa Olugbala ati igbe aye daradara ti ayipada yii mu baa (*Johanu 4:29) Bi o ṣe n tan imọlẹ yii kiri ni ọpọlọpọ awọn ara Samaria gba Jesu Kristi gbọ wọn sun mọ Kristi ati ọrọ Rẹ ti igbe aye ti wọn naa si yii pada.*

**Awọn Ẹkọ ti O Wa ninu Itan Obinrin Ara Samaria**

1. Biba Jesu Oluwa pade a maa mu ayipada ba eniyan. Ayipada kan ko le ba aye eniyan ni aijẹ pe o ba Jesu Oluwa pade. Jesu mu ayipada ba igbe aye obinrin ara Samaria nipa ṣiṣe alabapade Jesu Kristi ni ẹekanṣoṣo.
2. Ọlọrun n dahun awọn ibeere wa. *(Johanu 4:11 – 15)* Obinrin naa ri idahun si awọn ibeere ti o wa ninu ọkan rẹ nigba ti o beere wọn lọwọ Jesu. Bakan naa loni, a maa n ri idahun si awọn ibeere wa ti a ba yẹ Bibeli wo daadaa ti a si pe Ọlọrun fun iranlọwọ. Pọọlu gba Timoti niyanju lati kọ ẹkọ Bibeli daradara ki o le di aṣiṣe ti a yan ni otito *(Timoti 2:15).*
3. Gbigba Ọrọ Ọlọrun ti o n mu ayipada ba eniyan. Obinrin ara Samaria fẹran lati mọ ohun pupọ nipa Messiah gẹgẹ bi awọn ara Beri ninu Iṣe Awọn Aposteli, oun naa si gba ọrọ Kristi pẹlu ayọ; o ṣetan lati kẹkọọ ko dọgbọn ki o fi ara rẹ han bi ẹni mimọ, Lẹsẹkẹsẹ ni o jẹwọ ẹṣẹ rẹ ati igbagbọ ninu Oluwa.
4. Pipolongo gba awọn miiran la kuro ni ọrun apadi. Igbe aye titun yii jọ obinrin ara Samaria loju pupọ ti o si fi di pe o n lọ tọka ọna Messiah fun awọn eniyan gbogbo ọpọ eniyan ni o tẹti si ẹri rẹ nitori pe wọn ti ri igbe aye ọtun ni ara rẹ. Ẹ Kede Kristi nipa itankalẹ ihinrere awọn iṣẹ pataki, iwa ati iṣẹ rere.
5. Ẹ tan ki ẹ le mu iyipada ba igbe – aye awọn eniyan. Ẹni kọọkan ninu Kristi ni o jẹ imọlẹ Jesu obinrin naa di imọle ki o le mu ayipada ba igbe aye ọpọlọpọ. Nigba ti ẹyin ba gba aye titun ninu Kristi ti ẹ si n tan fun, yoo fa awọn eniyan si ọdọ ara Rẹ nipasẹ rẹ. O fẹ ki ẹ fi Oun han araye ki o le mu ayipada ba gbogbo eniyan Jesu Kristi ni anfani lati yi aye ọpọ eniyan pada tori pe obinrin ara Samaria pe awọn eniyan lati wa wo ẹni ti o mu eyi pada ba aye rẹ.

**Awọn Ọna Pataki Ti A Le Gba Jẹ Imọle fun Kristi**

Niwọn igba ti a ti gba yin la kuro ninu idapọ mọ aye ti Ọrọ Kristi ti mu ayipada bayin, ẹ ma a gbe igbe aye imọlẹ ti awọn eniyan yoo fi ri igbe aye titun yii, ẹ mu wọn wa si ọdọ Kristi ki aye ti wọn naa le yi pada. Ẹ Dide Tan Imọlẹ nipa ṣise ayipada ninu igbe aye ọtun wọnyi

1. Ẹ maa sọ nipa didara Oluwa. Ẹ maa jẹri fun Kristi (*Romu 10:14 – 17)* Ẹ maa sọ nipa ifẹ nla Rẹ, ẹbun igbala tati didara Rẹ siyin. Ẹ maa fi han araye pe ọtitọ ni Jesu Kristi ti o si dun ninu aye yin. Ẹ fi ọkan ran ipenija aye yoowu ti o le doju kọ yin. Ẹ maa koju ipenija aye ni aibẹru ṣugbọn pẹlu igboya *(Romu 8:26 – 28, Filipi 4:4 – 7)* Ẹ maṣe lugbadi ohun buburu kan
2. Ẹ gba Ọlọrun gbọ, ki ẹ si maa gbe igbesẹ bi o ti yẹ. Ẹ maa gbe ninu Ọlọrun nipasẹ adura. Ẹ maa gbadura ni aisinmi. Adura ni oore ọfẹ ti a fi le ṣegun aye ọsi yii *(Kolose 4:2 -4)*
3. Ẹ maa ṣe itọju ara ni ipa ọna Kristi. Ẹ jẹ alapẹẹrẹ rere *(Romu 2:21 – 24)*
4. Ẹ maa yọnda igbadun yin fun igbala ẹlomiran. Ẹ maa lo awọn anfani ti ẹ ba ni daradara *(Kolose 4:5 – 6)*
5. Ẹ maa darijin awọn ti o ba ṣẹ yin tabi pa yin lara, ẹ wa ni deede pẹlu Ọlọrun *(Kolose 3:13)*
6. Ẹ maa gbọran si aṣẹ Oluwa yin, Jesu Kristi ninu ohun gbogbo *(Kolose 3:22 – 25).*
7. Ẹ maa wa ojutu si aini ẹlomiran. Ẹ maa fẹran ọmọnikeji yin gẹgẹ bii si Jesu Olugbala wa.
8. Ẹ maa mu ẹlomiran dagba *(Timoti 4:12)*
9. Ẹ maa tan ihinrere kalẹ ki ẹ si maa gba awọn ọmọ Ọlọrun niyanju lati tun dagba si *(Romu 10:14 – 17).*
10. Ẹ maa ko ara yin ni ijanu ki ẹsi sọ ara yooku di ọmọ ẹyin tootọ. Ẹ maa gbọran si aṣẹ Ọlọrun ninu ohun gbogbo *(Kọrinti keji 10:16)*
11. Ẹ fẹ Ọlọrun tọkantọkan ki ẹ si sin – ln daradara *(Deutaronomi 6:5- 9, Romu 6:16 – 18)*
12. Ẹ maa dagba si ninu igbagbọ ati imọ ti Ọlọrun. Ẹ ma aka ọrọ Ọlọrun ni ojoojumọ ki ẹ le mọ ifẹ Rẹ.
13. Ẹ maa ṣe aṣaro ninu rẹ ni ọsan ati ni oru *(Kolose 3:16)*
14. Ẹ maa ja ija igbagbọ didara, Ẹ gbe igbe aye ti o tẹ Ọlọrun lọrun lojoojumọ *(Filipi 1:21)*
15. Ẹ maa fi ara yin si ipo ẹlomiran *(Heberu 13:1 – 3)*

## Ipari

Jesu wipe *"Ẹ yin ni iyọ aye … ẹ jẹ ki imọlẹ yin ki o mọlẹ to bẹ niwaju eniyan, ki wọn ki o le maa ri iṣẹ rere yin ki wọn ki o le maa yin Baba yin ti n bẹ ni ọrun" (Matiu 5:14 – 16).* Imọlẹ a maa tan. Aabo, idari ati itọni a maa wa ni ibi ti imọlẹ ba wa. Gẹgẹ bi imọlẹ, ẹ maa mu iyatọ ba agbegbe yin fun Kristi, idile, ibi iṣẹ, ọja ati agbegbe yin pẹlu.

## Ẹri

Mo padanu ọkọ mi Stuart M. Grant ẹni ti o tipasẹ aisan ọkan ku ni ọjọ kọkanla, oṣu kẹwaa ọdun 2007. Mo ti lero pe ko si ireti mọ paapaa pẹlu ọmọ marun-un, ti awọn mẹrin wa ni ile-iwe ni U.S.A. pẹlu ile-iṣẹ ti oṣiṣẹ rẹ le marun-un ni ọgọrun. Mo gbadura si Ọlọrun ọga ogo pe Oluwa ma ṣe jẹ ki agbara mi dinku awa mejeeji ni a mọ nipa aisan ọkan yii ti awọn oniṣegun eebo si ti sọ pe iṣẹ abẹ ni yoo ṣe ni South Africa owo iṣẹ abẹ yii pọ pupọ ti Stuart si sọ fun oniṣegun rẹ pe oun ko ṣetan lati na iru owo pupọ bayii lori aisan yii tori pe o ti pe ọmọ aadọrin ọdun nigba naa. O dun mi pupọ ati awọn idile. Lẹyin eyi Dokita eebo sọ fun Stuart pe ọsẹ mẹta pere ni o ku fun ni ori eepẹ. Iku ko tilẹ baa lẹru rara tori pe o ni igbagbọ ti o le koko. O ṣe eto ohun gbogbo pẹlu akọsilẹ ti o peye. Ni owurọ kutukutu ọjọ kọkanla, oṣu kẹwaa ọdun 2007 ti o dagbere fun aye, o gbadura fun mi gẹgẹ bi iyawo rẹ, o si wipe o digba. Ni akoko yii mo ro pe ireti ti pin ṣugbọn oore ọfẹ Rẹ ṣe iyanu ohun ti mo kọkọ ṣe ni pe mo gbadura lati dupẹ pe Ọlọrun fi Stuart fun mi gẹgẹ bi ọkọ, nigba ti o si ti gba a lọwọ mi yii igbagbọ mi ko ni ku. Ero ti o wa si ibi isinku pọ ṣugbọn (eeyan keeyan) eke ni awọn ti o pọ ju. Awọn miiran wa lati fi mi ṣe ẹlẹya pe o titan fun mi. Ko ye wọn pe igbẹkẹle mi wa ninu Ọlọrun ọkan lara awọn ọrẹ wa ti o sọrọ wipe iku Stuart jẹ opin irinajo kan. Omiran ti o sọrọ wipe kii ṣe opin nikan ṣugbọn ibẹrẹ irinajo miiran. Lẹsẹkẹsẹ ni igbagbọ mi ru soke. Mo ba pinnu lati mu igba ọtun ti ife Kristi yoo tan wa.

Lonii igbagbọ mi ti duro daadaa ju ti tẹlẹ lọ. Emi ni alakoso ati Oludari Agba Umozi- wa- Amayi apapo ile-iṣẹ yii wa ni Central Region, ọmọ igbimọ Agba Obinrin fun Ọjọ Adura ati ọpọlọpọ awọn ipo miiran ni mo dimu. Ọlọrun fi mi si awọn ipo wọnyi lati le gba awọn obinrin ni imọran ki n si ran wọn lọwọ. Aimoye awọn opo ni mo ti ṣe iranlọwọ fun ti iṣẹ iranṣẹ mi si n tẹsiwaju. Mo da ile-iwe alakọọbẹrẹ silẹ ni igberiko Mackenzle ti o si n ṣe daradara. Mo pa igbagbọ mo, ti okowo mi si n gbilẹ si daradara. Awọn ọmọkunrin mi meji ti wọn ti pari ẹkọ wọn ni Yunifasiti ti darapọ ti wọn si n ṣe daradara. Pẹlu oore ọfẹ Ọlọrun awọn mẹrẹrin ni wọn ti pari ẹkọ wọn ni Yunifasiti, eyi ti o kere ju ni o pari ẹkọ tirẹ ni ọdun yii, ẹyin arabinrin mi ni ijọ Onitẹbọmi mo n gba yin niyanju lati ma sọ ireti nu nigba ti iṣoro ba de ki adura yin maa jẹ "Oluwa maṣe jẹ ki igbagbọ mi dinkun ni akoko iṣoro." Ẹ gbe igbesẹ igbagbọ ki ẹ si gbagbọ pe Ọlọrun yoo tọju yin ti yoo si tun lo yin ninu ijọba Rẹ *(Luku 22:24 – 32)*

## Awọn Ẹbẹ Adura Ẹlẹkun Jẹkun

### Africa

1. Ẹ dupẹ lọwọ Ọlọrun fun bi Ọlọrun ṣe lo awọn Igbimọ alaṣẹ ti o n pari saa wọn ati awọn ti o n tẹwọ gba iṣẹ fun saa miiran pe ki Ọlọrun fi ọgbọn fun wọn lati ile ṣe iṣe naa bi Ọlọrun ṣe fẹ.
2. Ẹ gbadura fun awọn adari Oloṣelu ti wọn n gbe ofin kalẹ ati awọn iṣe lorisirisi pe ki wọn gba ẹmi Ọlọrun laaye lati dari wọn si awọn ofin ti o yẹ lati dẹkun iwa ibajẹ ti o tankiri ilẹ Africa.
3. Ẹ gbadura fun igbimọ Alaṣẹ ifarakinra ijọ Onitẹbọmi ni Africa (Africa Baptist fellowship) ati Akowe Agba bi wọn ṣe n dari.
4. Ẹ gbadura fun awọn ti o n daṣẹ silẹ kakakiri Africa pe ki awọn iṣẹ ti wọn n da silẹ jẹ eyi ti yoo ṣe awọn eniyan wọn ni anfani
5. Ẹ gbadura fun idasi Ọlọrun lori eto ọrọ-aje ti o dọrukọlẹ ni gbogbo ilẹ Africa.
6. Ẹ gbadura fun iṣẹ ihinrere ijọ Onitẹbọmi ni ilẹ North Africa ni ibi ti ẹsin Islamu ti fẹsẹ rin lẹ.

### Asia

1. Ẹ gbadura fun itusilẹ Ẹmi Mimọ ni Asia.
2. Ẹ gbadura fun isọkan laarin awọn Kristẹni ni Indoneṣia ki iwaasu ati ipolongo ihinrere le ni ipa ninu ijọba ilẹ naa ati awujọ wọn pẹlu.
3. Ẹ gbadura fun awọn Kristeni ni Sri Lanka peki wọn o le gbe ni irẹpọ pẹlu awọn ẹlẹsin miiran.
4. Ẹ gbadura pe ki Ijọ Onitẹbọmi Nepal lekọ ile ti ara wọn.
5. Ẹ gbadura fun igbaradi apejọpọ Ẹgbẹ Obinrin Ijọ Onitẹbọmi ti Asia ikẹtala iru rẹ. Ẹ gbadura ipese owo fun gbogbo awọn ikọ ti yoo kopa ninu eto naa ati yiyan awọn Oloye fun ọdun 2018 – 2023.
6. Ẹ gbadura idagba ẹmi fun awọn kristẹni ati ijọ gbogbo ni Bhutan ati aabo pẹlu

### Caribbean

1. Ẹ gbadura ipese iṣẹ rere fun awọn ọdọ ki wọn o si le fi ara wọn jin fun Ọlọrun.
2. Ẹ gbadura pe ki awọn obinrin ni oye ipe si iṣẹ Ọlọrun ki wọn o si le fi ara wọn jin bi wọn ti n gba A laye lati tan nipasẹ wọn.

3. Ẹ gbadura fun awọn obinrin papa awọn ti o jẹ ọdọ abilekọ lati fi ara jin fun iṣẹ adari ni agbegbe wọn ati ni orilẹ ede pẹlu.
4. Ẹ gbadura fun awọn obinrin ti wọn ti fi oju wina ibalopọ takọtakọ ni ọna aitọ ati awọn ti o ti ni iriri iwa inira ati aṣilo ninu ile. Ẹ gbadura igboya fun wọn lati dide ki wọn o koju awọn ti o n jẹ wọn niya ati awọn ọmọ wọn ki wọn o si le wa ọna aabo ti o peye.
5. Ẹ gbadura fun gbogbo ijọba ilẹ Caribbean pe ki wọn o le fọwọsowọpọ ṣiṣẹ fun idagbasoke awọn eniyan wọn.

## Europe

1. Ipenija wa niwaju fun ilẹ (Europe). Awọn alawọfunfun. Awọn orilẹ Ede wọn gbogbo ni o ni iriri inira, okunkun, ibanujẹ ati aifararọ akoko yii. Ẹ beere fun aanu, Alafia, adari rere, ti yoo le fi opin si awọn iwa ailaju, ipaniyan gbogbo. Ẹ gbadura pe ki Ọlọrun da awọn iwa iparun ti ko mọgbọn wa, ifaseyin ati iku ti o yii wọn ka duro.
2. Ẹ gbadura fun itura ọkan fun awọn ọkunrin, obinrin ati awọn ọmọde ti o farapa paapaa awọn opo, ọmọ orukan ti ogun ti sọ di ero ẹyin bi wọn sie n la awọn ọgbẹ, irora ati ipaya gbogbo kọja.
3. Ẹ gbadura pe ki Ọlọrun fun awọn kristẹni ti o wa labẹ inira satani ni itura ati okun lati duro gẹgẹ bi ọmọ ogun Kristi dopin. Ẹ gbadura pe ki ẹjẹ ati irubọ wọn jẹ irugbin fun ijọba Ọrun

## Latin America

1. Ẹ gbadura fun awọn ọṣọrọ adelebọ ninu ijọ pe ki ẹgbẹ obinrin le ṣe akiyesi idagba wọn(lọkan, lẹmi ati ni ara). Ẹ gbadura pe ki awọn adari ẹgbẹ obinrin le fi ara wọn jin fun imudagba awọn ọṣọrọ adelebo, ki wọn o le di ohun elo ti a mu dagba fun Ọlọrun
2. Ẹ gbadura pe ki ihinrere maa tẹsiwaju ni awọn ilẹ wa, ki Ọlọrun tun fun awọn Ẹgbẹ Obinnrin inu ijọ kọọkan ni okun.
3. Ẹ gbadura ifọwọkan Ọlọrun ni aye awọn alufa ati adari wa ati iṣẹ iranṣẹ wọn ni gbogbo ibi ti ilẹ Latin, America ba de.
4. Ẹ gbadura ipese ohun gbogbo ti iṣẹ ihinrere ti awọn obinrin elede Spanish yoo fi tẹsiwaju ni Latin America, Texas New York, ati New Jersey.
5. Ẹ gbadura fun awọn ọmọde ati ọdọ ni awujọ Latin America. Ẹ gbadura pe ki awọn obinrin Ijọ Onitẹbọmi Ṣetan lati se iṣẹ iranṣẹ wọn fun Ọlọrun ninu ohun yoowu ti wọn le maa la kọja.
6. Ẹ gbadura fun ohun gbogbo ti awọn obinrin Latin America yoo nilo fun idagba ati aṣeyọri awọn iṣẹ akanṣe ti wọn gbe kalẹ ni akoko yii, titi di ọdun marun-un.
7. Ẹ gbadura fun ọgbọn, ohun elo, okun ati ọna abayọ gbogbo ti o awọn igbimọ ẹgbẹ obinrin Onitẹbọmi ilẹ Latin America nilo.

## North America

1. Ẹ gbadura fun ẹmi ifọkansin ati ififunni fun awọn obinrin Onitẹbọmi bi wọn ṣe n ran awọn alarinkiri ti ko nile lori ti wọn n de si ilẹ North America lojoojumọ ti wọn si n tẹwọ gba wọn
2. Ẹ gbadura fun ọkẹ aimọye idile ti wọn pa danu ati awọn obinrin aimọye ti wọn jẹ ọmọ Orilẹ naa ti wọn sọnu kaakiri ilẹ North America ti ọrọ wọn si wa lọdọ awọn agbofinro (Ọlọpa)

3. Ẹ gbadura fun irẹpọ laarin awọn obinrin Onitẹbọmi North America pe ki wọn o le maa gba ara wọn niyanju lati ṣiṣẹ pọ fun kikọ Ijọba Ọrun.
4. Ẹ gbadura fun aabo Ọlọrun lori awọn ọdọmọbinrin kuro lọwọ awọn ti o nfi awọn ọdọbinrin ṣowo.
5. Ẹ gbadura pe ki ọdọ ati agba obinrin Onitẹbọmi jigiri si aini ẹnikeji wọn.
6. Ẹ gbadura pe ki awọn obinrin Onitẹbọmi mu ojuṣe wọn ni ọkunkundun lati tọju ayika wọn ki wọn o si fi apẹẹrẹ iṣẹ iriju rere si awọn ohun ti Ọlọrun ṣẹda lelẹ.

**South West Pacific**

1. Ẹ gbadura itusilẹ fun awọn ti wọn lugbadi wahala oṣelu, iwa jagidijagan, ilokulo obinrin ati ọmọde ni West Papua ati Papua New Guinea.
2. Ẹ gbadura iṣọkan laarin awọn adari inu ijọ Onitẹbọmi Papua eyi ti o ni ipa lori idari ati iṣọkan awọn obinrin.
   Ẹ gbadura fun ọkan Ọlọrun fun awọn obinrin ti o n dari lati le sọrọ lori ẹdun ọkan awọn obinrin ti wọn n dari
3. Ẹ gbadura fun awọn obinrin Onitẹbọmi Austiralia bi wọn ti n ṣe akitiyan lati rii pe awọn ọṣọrọ adelebọ ko ipa, ti wọn si n gba idanilekọọ lori ipo adari pe ki wọn o si le maa ṣe abẹwo si igberiko lati gba awọn obinrin igberiko niyanju.
4. Ẹ gbadura fun awọn obinrin Fiji bi wọn ṣe n koju atubọtan iji lile ti o ṣẹṣẹ waye, ẹlẹẹkeji iru rẹ, bi wọn ṣe tun ti gba ojuṣe miiran ti wọn n wa ounjẹ, omi, ilegbe ati ọna ati ri owo.
5. Ẹ gbadura fun awọn obinrin Onitẹbọmi ẹkun kọọkan paapaa julọ Australia ati New Zealand lati darapọ mọ ẹdun ọkan awọn obinrin agbaye ni Ọjọ adura.
6. Ẹ gbadura fun ipese fun awọn obinrin ti o n ṣe abẹwo si ọdọ awọn obinrin igberiko ti wọn ko le darapọ mọ awọn ipade gbogbo.

## Ẹbẹ Adura Gbogbo-Gboo

## Igbimọ Ẹgbẹ Ijọ Onitẹbọmi lagbaaye

1. Ẹ gbadura fun idari ẹka Ẹgbẹ Obinrin Onitẹbọmi ni Agbaye fun iṣẹgun lori awọn ipenija ti ẹka ẹgbẹ obinrin n koju lọwọlọwọ.

**Awọn Oloye Agbaye (2015-2020)**
**Alaga:** Ksenija Magda
Email: president@bwawd.org
**Akọwe/Akapo:** Kathy E. James
Email: Treasurerwd@bwawd.org.

**Awọn Igbakeji Alaga**
**Africa:** Joina Dhlula
Email: Joinadhlula@gmail.com
**Asia:** Precy T. Caronongan
Email: Caronongan.precy@gmail.com
**Caribbean:** Yvonne Pitter
Email: Jupitter@hotmail.com
**Europe:** Aniko Ujvari
Email: Ebwu.president@gmail.com
**Latin America:** Sara de Barrios
Email: Saradebarrios@hotmail.com
**North America:** Moreen Sharp
Email: President@nabwu.org
**South West Pacific:** Amelia Gavid
Email: Agavidi@gmail.com
**BWA Women's Department**
Email: Womenbwa@bwawd.org

2. Ẹ gbadura fun adari agba fidiẹ, Moreen Sharp, bi o ṣe n gba iṣẹ naa ṣe ninu Ijọ Falls ni ẹka awọn obinrin, ki Ọlọrun pese ohun gbogbo ti yoo nilo ki ọgbọn Ọlọrun jẹ tirẹ pẹlu ati okun pipe fun iṣẹ naa. Bakan naa ẹ gbadura fun idari Ọlọrun bi wọn ṣe n ṣiṣẹ lori yiyan oludari agba tuntun ati igbimọ rẹ.
3. Ẹ gbadura fun ipade awọn Adari ni agbaye ti yoo waye ni Rio de Janeiro ni ọdun 2020, bi ipalẹmọ ṣe bẹrẹ ti awọn ipinnu lọkanojọkan ti bẹrẹ. Ẹ gbadura pe ki Ọlọrun ran awọn adari gbogbo lọwọ lati mu erongba mimu ẹgbẹrun meji awọn obinrin papọ. Ẹ gbadura fun aṣeyọri ajọyọ Ẹgbẹ Obinrin Onitẹbọmi lagbaaye ni ọdun 2020. Eyi ti yoo tẹle ipade nla wa.
4. Ẹ gbadura fun alaga Obinrin Onitẹbọmi lagbaaye, Paul Msiza ati akọwe agba Meville Callam ati gbogbo ẹka obinrin Onitẹbọmi lagbaaye bi wọn ṣe n gbaradi fun yiyan Akọwe Agba titun.

**Itẹnumọ awọn Iṣẹ Pataki Ọjọ Adura lagbaaye ni Ọdun 2017, Africa**

1. **Orukọ Iṣẹ Pataki:** Ẹ ran awọn ọmọbinrin igberiko wa lọwọ lati kọ ẹkọ
   **Orilẹ Ede:** Liberia.
   **Ẹgbẹ:** F.C. Barnes Indusrial Academy (awọn obinrin Onitẹbọmi Liberia)
   **Agbatẹru Iṣẹ Naa:** Olivia B. Hill
2. **Orukọ Iṣẹ Pataki:** Ilodi si ilokulo ọmọde.
   **Orilẹ Ede:** Malawi
   **Ẹgbẹ:** Tisule Foundation
   **Agbatẹru Iṣẹ:** Patricia Annie Mzumara
3. **Orukọ Iṣẹ Pataki:** Itọrẹ Aanu
   **Orilẹ Ede:** South Africa
   **Ẹgbẹ:** First City Baptist Church
   **Agbatẹru Iṣẹ:** Donnae Thomas
4. **Orukọ Iṣẹ Pataki:** Ṣiṣẹ Agbekalẹ iibakẹgbẹ awọn obinrin Bhutan
   **Orilẹ Ede:** Bhutan
   **Ẹgbẹ:** Ẹgbẹ Obinrin Onihinrere Asia
   **Agbatẹru Iṣẹ:** Precy Caranongan; Zirsangliana Ralte

**Gbigba Ọrẹ**

**Orin**

**Adura ati Oore Ọfẹ**